# Ẹ̀rọ Ayára bíi àṣá (Kọ́ǹpútà)



## Ẹ̀kọ́ àwọn ẹ̀yà ayára bíi àṣá



Ẹ̀rọ ìtẹ̀wé aláfọwọ́tẹ̀ yorùbá fi tẹ gbogbo ọ̀rọ̀
Yorùbá keyboard email contact@omoluwabi.org

# Àyára bíi àṣá

## I Ìfihàn




Gbogbo àwọn ẹ̀rọ tí a ń lò lónìí máa ṣiṣẹ́ bákan náà ( Àyára bíi àṣá , fóònù àyárà,...).

## II Àwọn ẹ̀yà ẹ̀rọ àyára bíi àṣá

1) Ìbo̱jú

Ẹ̀rọ ìbo̱jú jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀rọ agbègbè ti ìjáde, a ń pè bẹ́ẹ̀ nítorí pé àwọn iró ti a bá tẹ̀ pẹ̀lú ẹ̀rọ ìtẹ̀wé aláfọwọ́tẹ̀, orí ẹ ni tí ń jáde. Àwọn ẹ̀rọ ìbòjú pé oríṣi, ìbòjú ( ”14, ”17, “24 … ). Orúkọ àwọn ilé iṣẹ́ ti ń yọ wọn jáde ni ( Samsung, Sony, Sharp, Nec, HP… ).

Àkiyèsí: “14 jẹ́ àtaǹpàkò mẹ́rìnlà

2) Ẹ̀rọ ìtẹ̀wé aláfọwọ́tẹ̀

Ẹ̀rọ yì jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹ̀rọ ìwọlé, nitórí wípé àwọn iró tí a bá tẹ̀ wọlé máa ń gbà orílé iṣẹ́ kọ́ǹpútà fi jáde sórí ìbòjú.
Àwọn ẹ̀rọ ìtẹ̀wé aláfọwọ́tẹ̀ ti a ń lò fi kọ èdè Faransé, orúko wọn ni AZERTY , èyí ti a ń lò fi kọ èdè gẹ́ẹ̀sì, orúkọ ẹ ni QWERTY, fi kọ èdè Yorùbá tàbí àwọn èdè ìlú adúláwọ̀ ẹ̀rọ ìtẹ̀wé aláfọwọ́tẹ̀ EITWA ti ilé iṣẹ́ EITWA ni a ń lò.
Pẹ̀lú ẹ̀rọ ìtẹ̀wé EITWA a tún lè kọ Faransé, Gẹ́ẹ̀sì, àti gbogbo èdè ìlú adúláwọ̀ bíi 2000.

**3) Orílé iṣẹ́ kọ́ǹpútà**


Ẹ̀yà pàtàkì kan ni ẹ̀ya yìí jẹ́, inú ẹ̀yà yìí ni àwọn ẹ̀yà mí ìn ti wọn tún ṣe pàtàkì fún ìṣiṣẹ́ kọ́ǹpútà wà. Àwọn èyà wọ̀nyìí ni :

**3,1) amúnáwá ( Generator )**



Ẹyà òpèsè iná mànàmáná  yìí ni máa mú iná wá fún ẹ̀rọ àyára bíi àṣá, tí kò bá ṣiṣẹ́, tó bá dáṣẹ́ dúro, iná kò níí wá inú kọ́ńpútà mọ́, á sì dáṣẹ́ dúro. Inú orílé iṣẹ́ ló wà, àmọ́ wọ́n máa ń tà á lọ́tọ̀ọ́. Amúnáwá máa dín agbára òpèsè iná gbogbogbò kù, agbára yìí máa kúrò ni fọ́ltì 220 fi dé fọ́ltì 5 tàbí fọ́ltì 12.

**3.3  Ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́  ( procesor )**




Ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́ jẹ́ nǹkan pàtàkì fún kọ́ńpútà inú orílé iṣẹ́ ló wà. Ti a bá fẹ́ fi ẹ̀rọ ayára bíi àṣá wé èèyàn, a yóò sọ pé , nǹkan ti ọkàn jẹ́ fún èèyàn ni ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́ jẹ́ fún ẹ̀rọ kọ́ńpútà. èyí fi hàn pé ẹ̀yà pàtàkì ni.Ti ẹ̀rọ yìí bá dáṣẹ́ dúro, kọ́ńpútà pàápàá kò níí ṣiṣẹ́ mọ́.
Inú ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́ yìí ni àwọn ẹ̀yà mí ìn tún wà :
- ẹ̀yà ẹ̀rọ  àfikún  +
- ẹ̀yà ẹ̀rọ  ìyọ̀kù    –
- ẹ̀yà ẹ̀rọ  ìlọ́po     *
- ẹ́yà ẹ̀rọ  pìpín     /

Àti  àwọn ẹ̀yà ẹ̀rọ mì ín.
Gbogbo àwon ẹ̀yà wọ̀nyìí ni kọ́ńpútà  máa ń lò fi ṣe gbogbo àwọn ìṣirò lọ́lọ̀kanòjọ́kan, pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ mì ín.
Àwọn ilé iṣẹ́ ti ń rọ àwọn ẹ̀rọ wọ̀nyìí ni  INTEL, IBM, AMD, CENTAUR, TEXAS…
INTEL ló ṣíwájú  gbogbo àwọn ilé iṣẹ́ wọ̀nyìí ni gbogbo àgbáyé. Ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ àwon kọ́ńpútà tábìlì àti àwọn kọ́ńpútà alágbéka ni wọ́n ń lò ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́ INTEL, àwọn ìwọ̀n kan ni ń lò AMD àti àwọn èyì tó kù.

**3.2 aago**

Aago yìí ni ẹ̀rọ ìṣe ( procesor )  máa ń lò fún ètò iṣẹ́ rẹ̀, bí tí aago yìí bá ṣe yara ṣiṣẹ́, bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀rọ ayára bíi àṣá náà máa yara. Àwọn ẹ̀rọ tí wọ́n ń tà lónìí:  àgbóhunsáfẹ́fẹ́ wọn ni Ghz 4 dé 8.
àmọ́ agbóhunsáfẹ́fẹ́ yìí máa lọ sókè  lóṣù mẹ́fà mẹ́fà.


### 3.4 Ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ ( RAM )

**Ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ (** RAM )



Inú ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ tí orúkọ rẹ̀ ń jẹ́ RAM ( Random Access Memory ) ni a máa ń kó àwọn ìsọfúnni “dátà” ti a bá fẹ́ lò lẹ́sẹ̀kẹ́sẹ̀ pamọ́ sí, a lè kọ “dátà” sínú ẹ̀rọ yìí, a sì tún lè kà á. Nitórí ẹ ni wọ́n fi fún ni orúkọ RAM (Random Access Memory) ìtúmọ̀ ṙẹ ni ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ ti a lè kọ, ti a sì tún lè kà. Bíi àpẹẹrẹ tí ẹ̀rọ ìṣe bá fẹ́ ṣẹ ìṣirò 2+3, tó bá fẹ́ fi méjì fi kún mẹ́tà tí yóò jẹ́ marún ùn , yóò kà 2 sínú ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ yìí tí, lẹ́yìn èyí á yóò ka 3 tí a tún gbé pamọ́ sínú ẹ̀rọ yìí, lẹ́yìn ẹ, yóò wa fi méjì fi kún mẹ́tà ti ń jẹ́ marún ùn, yóò wà kọ ọ́ sínú ẹ̀rọ ibi ìpamọ́. Ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́ ìṣirò lè fi marún ùn yìí hàn lórí ẹ̀rọ ìbòjú. Go 4 dé 8 ni agbára ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ tí àwọn kọ̀ńpútà ń lò, n òde onìí.
Ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ yìí dàbí tábìlì fún ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́ ( procesor ) ti kọ̀ńpútà , inú rẹ̀ ni máa ń kó àwọn “data” tó bá fẹ́ lò fi ṣiṣẹ́ lẹ́sẹ̀kẹ́sẹ̀ sí.
Tí ẹ bá ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú kọ̀ńpútà, ẹ máa rántí láti máa dà “dátà” tó wà nínú ẹ̀rọ ìrantí sínú àwo líle. Bí kò ṣe bẹ́ẹ̀, ẹ yóò pàdánù gbogbo iṣẹ́ ti ẹ ṣe sẹ́yin wà lọ.

### 3.5 Ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ ( ROM )



Ìtúmọ̀ ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ ROM ( Read Only Memory ) ni ẹ̀rọ ti a lè kà àmọ́ ti a kò lè kọ. Ilé-iṣẹ́ tí ń rọ kọ̀ńpútà ni máa kọ àwọn ètò yẹn si lórí. Ètò ìpìlẹ̀ ni wọ́n máa ń kó si lórí, orúkọ ètò ìpilẹ̀ yẹn ni BIOS ( Basic Input Output system ) ìtúmọ rẹ̀ ni ètò ìpilẹ̀ ti ìwọ́lé àti ti ìjáde. Àwọn ètò ìpìlẹ̀ yẹn ni máa ń ṣe ìṣakósó gbogbo àwọn ẹ̀rọ agbègbè ayára bíi àṣá nígbà ti ó bá bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́. Ẹ̀rọ ètò ìpìlẹ̀ BIOS yìí ni kọ́kọ́ máa ń bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ nígbà tí ẹ bá tan kọ̀ńpútà yín, lẹ́yin ẹ ni àwọn ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́ DOS àti WINDOWS máa wá wọṣẹ́.


### 3.6 Àwọn wáyà ìtanná ( Bus )

Àwọn wáyà ìtánna ni a máa lò fi so àwọn ẹ̀yà ayára bíi àṣá ( procesor, ẹ̀rọ ìránti ROM, ẹ̀rọ ìránti RAM...) pọ̀. A máa kó gbogbo àwọn ẹ̀yà wọ̀nyìí ti a so pọ̀ sórí káàdì ti a pè ni ìyá káàdì.

Wáyà ìtanná oríṣi mẹ́tà ló wà :

- Wáyà ìtanná dátà ( Inú wáyà yìí ni a máa kọ́ àwọn iró ọ̀rọ̀ gbà )
- Wáyà ìtanná òpópónà ( Inú wáyà yìí ni a máa gbé adírẹ́sì ẹ̀yà ibi ìpamọ́ ti a fẹ́ lò gbà)
- Wáyà ìtanná ìpàṣẹ ( Inú wáyà yìí ni a máa gbé àṣẹ ìfiṣiṣẹ́ àwọn ẹ̀yà kọ̀ńpútà gbà )

Wáyà ìtanná



**3.7  àwo gbàgidi**

Àwo gbàgidi
( Hard Disc )





Àwo gbàgidi jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀yà orílé iṣẹ́ kọ́ńpútà, ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ tí agbára rẹ̀ pọ̀ gan an ni, inú rẹ̀ ni a máa ń kó àwọn iṣẹ́ ti a bá ṣe pamọ́ sí, àwo gbàgidi yìí  jẹ́ gẹ́gẹ́ bíi àpótí nígbà ti ẹ bá pari iṣẹ́ yín tán,  inú rẹ̀ ni  ẹ yóò kó àwọn iṣẹ́ yín pamọ́ sí.  Agbára àwo gbàgidi ti wọ́n ń tà lónìí ni Gb 500 . Bí tí agbára yẹn ṣe ga, bẹ́ẹ̀ ni ó ti lè gbà ọ̀pọ̀ iṣẹ́ ti ẹ bá parí.
Ẹ má gbàgbé láti máa kó iṣẹ́ ti ẹ bá ń ṣe lọ́wọ́ pamọ́ sí orí àwo gbàgidi yìí, bí kò bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ ti kọ́ńpútà yín bá kọṣẹ́, tàbí ti ẹ bá pa kọ́ńpútà láì kó iṣẹ́ yín pamọ́, ẹ yóò pàdánù gbogbo iṣẹ́ yín.

**III  àwọn ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ agbègbè mí ìn**

**1) Kọ́kọ́rọ́ USB**

Kọ́kọ́rọ́ USB




Kọ́kọ́rọ́ USB jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ alágbára, bíi ẹ̀rọ àwo gbàgidi, nígbà tí ẹ bá ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú kọ́ńpútà yín, ẹ yóò lè  kó àwọn iṣẹ́ tí ẹ parí sínú USB.
Agbára àwọn kọ́kọ́rọ́ tí wọ́n ń tà lónìí ni ( Gb 4, Gb 8, Gb 16, Gb 32 ... ).
Kọ́kọ́rọ́ USB  dàbí ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ alágbára àlágbéka, a lè lò níbi gbogbo.

## 2) CD DVD




Ẹ̀rọ ibi ìpamọ́ ni àwọn CD pẹ̀lú DVD. Iṣẹ́ ti ẹ bá ṣé lórí kọ́ńpútà yín, ẹ lè kó sórí CD àti DVD wọ́nyìí. Orí CD àti DVD ni a máa ń kó àwọn orin pẹ̀lú fídíò sí.
Agbára àwọn CD DVD ti a ń lò lónìí ni Mb 720 àti Gb 4.
A ò tún lò àwọn ibi ìpamọ́ wọ̀nyì mọ́.

### 3) Ìhò USB

Ìbùdo USB




USB ( Universal Serial Bus )

Ìhò USB ní máa ń fún wa ní àǹfààní láti so àwọn ẹ̀rọ mì ín mọ́ orílé iṣẹ́ kọ́pútà. Àwọn ìhò USB yìí ni wọ́n ń lò gan an lónìí. Lẹ́yin èyí, a tún ni àwọn ìhò pọ̀gbà àti tẹlẹ́ńtẹlé tí a ò tún sábà lò mọ́. Orílé iṣẹ́ kọ́ńpútà máa ń lò àwọn ìhò wọ̀nyì láti  fi àwọn báítì ránṣẹ́ sí àwọn ẹ̀rọ tí ń bá ṣiṣẹ́.

4) Ẹ̀kúté atọ́ka



Pẹ̀lú èkúté atọ́ka ni a máa ń ṣiṣẹ́ lórí ìbojú ẹ̀rọ ayára bíi àṣá. Àwọn èkúté atọ́ka máa ń lò ìhò USB. Àwọn atọka mí ìn máa ń lò ìhò pọ̀gbà , tàbí ìhò tẹlẹ́ńtẹlé. Tí ẹ bá fẹ́ so asín pọ̀ mọ́ orléÀpótí iṣe, ẹ jẹ́ kó dá yín lójú pé ìhò USB kan lé sílẹ̀. Ìhò yìí ni asín máa ń lò fi fi báítì ránṣẹ́ sí ẹ̀rọ ìṣe tàbí fi gbà báítì wá́ láti òdọ̀ rẹ̀.

### 5) Ẹ̀rọ ìtẹ̀wé títẹ̀ sítà



Ẹ̀rọ ìtẹ̀wé títẹ̀ sítà  jẹ́ ọ́kan lára àwọn ẹ̀rọ ìjáde gẹ́gẹ́ bíi ìbòjú. Iṣẹ́ ti a bá ṣe lórí ẹ̀rọ ayára bíi àṣá, ẹ̀rọ ìtẹ́wé títẹ̀ sítà ni a yóò fi yọ ọ́ jáde. Ọ̀pọlọ̀pọ̀ àwọn ẹ̀kà ìtẹ̀wé títẹ̀ sítà ló wà , àwọn ilé iṣẹ́ ti ń yọ wọn jáde ni ( Sony, HP, Kanon …) .

**6) Olùkà DVD**



Nígbà tí a bá fẹ́ ka DVD tàbí CD inú ẹ̀rọ olùkà yìí ni a máa ń fi sí , òun náà wà lára àwọn ẹ̀rọ ìwọlé bíi ẹ̀rọ  ìtẹ̀wé aláfọwọ́tẹ̀.

**7) Ìhò pọ̀bà ( Parralel port )**




A ò tún sábà lò àwọn ìhò ìwọ̀nyẹn,  àwọn ẹ̀rọ ìtẹ́wé títẹ̀ síta jáde, àwọn ẹ̀rọ skani ti a ń lò nígba kan, ni wọ́n máa ń lò àwọn ìhò wọ́nyìí.

**8) Tẹléńtẹlé ìhò  ( Serial port )**


teléńtelé ìhò ( serial port )

Àwọn ìhò tẹléńtẹlé yẹn, wọ́n kò tú́n fi bẹ́ẹ̀ lò wọ́n mọ́ , àmọ́ àwọn ẹ̀rọ mì ín sì tú́n ń lò wọ́n.
Nítorí nǹkan tí a fi pè wọn ni ìhò tẹléńtẹlé, àwọn bíìtì tí ń gbà inú wọn máa ń tẹ̀lé ara wọn ni ẹ̀yọ kọ̀ọ̀kan.

**9) Skani**

Àwọn ẹ̀rọ yẹn pé oríṣi àwọn olówó ńlá wà , àwọn olówó kékeré sì tún wà, àmọ́ ni òde onìí àwọn ẹ̀rọ ìtẹ̀wé títẹ̀ sítà máa ń rọpò skani yìí. Àwọn skani yìí máa ń yọ àwọn àwòrán jáde.
Àwọn ilé iṣẹ́ ti ń yọ wọn jáde ni ( canon, sony, sharp…).



**IV Àwọn kọ́ńpútà àti àwọn ẹ̀rọ EITWA**

**1) Ìfihàn**


Àwọn ẹ̀rọ ayára bíi àṣá àti àwọn fóònu ayára EITWA rọrùn láti lò.
Ti ẹ bá fẹ́ kọ èdè yorùbá bó ṣe tọ àti bo ṣe yẹ, àti èdè àwọn ìlú adúláwọ̀ gbogbo àwọn ẹ̀rọ ìtẹ́wé aláfọwọ́tẹ̀ ilé iṣẹ́ EITWA ni kí ẹ lò.
Kí ẹ tó lò àwọn ẹ̀rọ wọ̀nyìí, ẹ ní láti kọ bí tí wọ́n ń ṣe ṣiṣẹ́.

2) **Àwọn ẹ̀rọ ìtẹ̀wé aláfọwọ́tẹ̀ EITWA**




**3) Àwọn oríṣi bọ́tìnnì**

**3.1 Bọ́tìnnì oní ìpele méjì**




Ìpele àkọ́kọ́ ni "a" kékereé a ò kọ ọ́ sí orí bọ́tìnnì yìí nítorí kó má gbàyè jù.
Ìpele èkejì ni "A" ńlá, ti a kọ sókè.
Nígbà tí ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "a", a kékeré sí ojú ìbòjú ẹ kàn tẹ̀ bọ́tìnnì yìí ni.
Nígbà tí a bá fẹ́ tẹ̀ "A", A ńlá sí ojú ìbòjú ẹ tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tìnnì "Shift" pápọ̀


### 3.3 Bọ́tìnnì oní ìpele mẹ́ta




Níbi ìpele àkọ́kọ́ ni ";" agbọ̀nrin.
Ìpele èkejì ni "." ojúami.
Ìpele ẹkẹ́ẹ̀tà ni ">" tóbi jú.

Nígbà tí ẹ bá fẹ́ tẹ̀ ";" agbọ̀nrin sí ojú ìbojú ẹ yóò kàn tẹ̀ bọ́tìnnì yìí ni.
Nígbà tí ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "." ojúami sí ojú ìbojú ẹ yóò tẹ̀ bọ́tínì yìí àti bọ́tìnnì "Shift" lápapọ̀.
Ti ẹ bá fẹ́ tẹ̀ ">" tóbi jù sí ojú ìbòjú ẹ yóò tẹ̀ bọ́tínì yìí àti bọ́tìnnì "Alt" ti apá ọ̀tún lápápọ̀.

### 3.4 Bọ̀tìnnì oní ìpele mẹ́rin





Níbi Ìpele àkọ́kọ́ ni "ẹ" kékeré wọ́n kò kọ ẹ sí orí bọ́tínì yìí nítorí ko má báa gbàyè jù.
Ìpele èkejì ni "Ẹ" ńlá.
Ìpele ẹkẹ́ẹ̀tà ni "q" kékeré.
Ìpele ẹkẹ́rin ni "Q" ńlá.

Nígbà tí ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "ẹ" ẹ kékeré sí ojú ìbòjú, ẹ yóò tẹ̀ bọ́tínì yìí ni.
Nígbà tí ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "Ẹ" Ẹ ńlá sí ojú ìbòjú ẹ yóò tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tìnnnì "Shift" Lápapọ̀.
Nígbà tí ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "q" q kékeré sí ojú ìbòjú, ẹ yóò tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tìnnì "Alt" ti Apá ọ̀tun pàpọ̀.

Nígbà tí ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "Q" Q ńlá sí ojú ìbòjú ẹ yóò tẹ̀ bọ́tínì yìí àti bọ́tínnì "Alt" ti apá Ọ̀tun àti bọ́tìnnì "Shift" mẹ́tẹ̀tà lápapọ̀.

### 3.3 Bọ́tìnnì àmì

Pẹ́lù bọ́tìnnì yìí ìyàtọ̀ diẹ́ wà, a má lò bọ́tìnnì yìí fi fi àmì sí orí àwọn iró , kí ẹ tó lò bọ́tìnnì yìí ẹ yóò tí tẹ̀ bọ́tìnnì iró ti ẹ fẹ́ kọ, lẹ́yin náà ẹ wá fi àmì sí orí ẹ.




Níbi ìpele àkọ́kọ́ ni "´" ohùn kúkúrú.
Ìpele èkejì ni "`" ohùn pàtàkì.
Ìpele ẹkẹ́ẹ̀ta ni "ˇ" ohùn àkíyèsì.
Ìpele ẹkẹ́rin ni "˜" ohùn ìtọ́sí.

Nígbà tí ẹ bá fẹ́ fi àmì "´" ohùn kúkúrú sí orí "o" bi àpẹrẹ, ẹ yóò ti tẹ̀ "o" yẹn sí ojú ìbòjú, ẹ yóò kàn wá tẹ̀ bọ́tìnnì yìí nígbà yẹn sorí "o" ti ẹ ti kọ, yóò wa di "ó".
Nígbà tí ẹ bá fẹ́ fi àmì "`" ohún pàtàkì sí orí "o" ti ẹ ti tẹ̀ sí ojú ìbòjú bi àpẹrẹ, ẹ yóò tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tínnì "Shift" lápapọ̀ Nígbà yẹn ni ẹ wà kọ "ò".
Nígbà tí ẹ bá fẹ́ fi àmì "ˇ" ohùn àkíyèsì sí orí "o" ti ẹ tí tẹ̀ sí ojú ìbòjú bi àpẹrẹ, ẹ yóò tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tìnnì "Alt" ti apá ọ̀tún lápapọ̀ nígbà yẹn ni ẹ yóò wá kọ "ǒ".
Nígbà tí ẹ bá fẹ́ fi àmì "˜" ohùn ìtọ́sí sí orí "o" ti ẹ ti tẹ̀ sí ojú ìbòjú bi àpẹrẹ, ẹ yóò tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tìnnì "Alt" ti apá ọ̀tún àti bọ́tìnnì "Shift" mẹ́tẹ̀tà lápapọ̀. nígbà yẹn ni ẹ yóò wa kọ "õ".